# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO. 878 LAGOS SATURDAY JULY 20 JULY 26 KOBO MEJI (2D) 1963


**ELEYI ARA!**

# Baba Ole Kan Ni Pota Lo Sewon Tomo Tomo

PORT-HARCOURT—Orisirisi nkan ni o nṣẹlẹ lojojumọ ni ilu Port-Harcourt nibi, eyi ti o ṣelẹ ninu ọsẹ yi ni ti baba onişowo kan ti awọn ọlọpa mu pẹlu awọn enia kan ti nwọn ni nwọn ji apo iwe iṣẹ Oyinbo kan gbe, ti ọdaran na bẹ adajọ, Ọgbẹni E. A. Ita, wipe ki o jẹ ki on lọ sẹwọn ti o sọ on si tọmọ tọmọ ti iyawo on bi fun on.

Mathew Okeke ni orukọ ọdanran na, ẹni ọdun mẹdọgbọn nişe, ẹwọn oşu mejila ni adajọ na sọ si fun ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pẹlu awọn ọrẹ rẹ meji, Godffrey Abanodii ati Peter Ofoedu, ti nwọn ni nwọn jọ pawọpọ jale na; ẹwọn oşu mejila mejila ni adajọ Kotu ọlọpa sọ awọn na si.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ti nwọn mu, wọn ro niwaju adajọ ni wipe Oyinbo ajoji kan ti orukọ rẹ njẹ Valerio Sanfamicone de si ile ero kan ti nwọn npe Cebar Palace pẹlu ẹru rẹ, awọn ole yi si foju da apo iṣẹ rẹ, ti o nfẹ lọwọ kiri nwọn ṣebi owo ni o di sibẹ, nwọn ko mọ iọwọ.

Eyi ti o jẹ nkan ara ninu ẹjọ na nipe lọjọ tiadajọ ti nwọn ro ẹjọ yi niwaju rẹ nsa konko mọ wọn, ọkan ninu awọn ọdaran na, Okeke, ni on ko kọ lati lọ sẹwọn, ṣugbọn ki adajọ yi jọwọ ki o jẹ ki on ko awọn ọmọ on mẹtẹta dani nitoripe iya wọn ti kọ on silẹ, ko si si ọrẹ tabi ẹbi ti o le ba on tọju wọn.

Adajọ na gba fun un wipe ki o lọ tile tile. Onirohin wa ni iru iwe aṣẹ ti awọn ọlọpa yio fi mu awọn ọmọ mẹtẹta na wọ ọgba ẹwọn ni ko ti wa si.

---

## Adesina Ọbake Titun De!

ABẸOKUTA | A gbọ wipe awọn afọbajẹ ilu Ẹgba ni igun mẹrẹrin Abẹokuta tişe ipade, nwọn si ti jiroro lati fi Ọmọba Samueli Adeşina Gbadebọ si ipobi

**Wo yoku loju ewe kejo**

## Akiyesi

**Awon Dokita Fanke Kori Lori Eto ilera tuntun ilu Eko ti Majekodunmi se**

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

**Ofin Tuntun De!**

## Awon Loya Agbejoro Wo Gawu Lodo Ijoba

IBADAN— Awọn onikẹkẹ akẹru ọmọlanke ni a gbọ wipe nwọn ma ngbawe lọdọdun pẹlu owo, ofin tuntun ti de fun awọn lọya (layer) agbejẹro papa nisisiyi wipe awọn na ni lati ma fi owo gba owo-aşẹ lọdọdun ki nwọn to le ma sọrọ niwaju adajọ ni Ibadan tabi nibikibi ni ilẹ ia

Akọwe onirohin Eleti—Ọfẹ ni on gbọ wipe nwọn ti yan awọn akọwe sode lati ma gba owo iwe-aşẹ yi lọwọ awọn lọya agbẹjọro yi, nwọn si ti fi iwe ikilọ sode wipe lọya ki lọya ti ko ba tete sanwo ti rẹ, ki o gba iwe-aşẹ (licence) sọwọ ki oşu ti mbọ to pari, a jẹ wipe oluwa wọ gawu; o le de kotu ki o oko ma wo nkan ti nwọn ba nşe, şugbọn ko gbọdọ mi fin niwaju adajọ Kotu na.

Awọn lọya kan ti mo ba pade ni Kotu awọn ọlọpa ni Onikere ni ọrọ a ngbawe aşẹ lọdọdun ki a to şe işẹ ni Kotu yi ko ye awọn, nwọn ni bi awọn alakoso Ijọba ba nwa owo ti nwọn yio na fun eto ilọsiwaju ilu ko nşe ọna ai ni o yẹ ki nwọn gba yara. Nwọn ni işẹ lọya ki şe işẹ awọn alagbẹdẹ golu tabi ọlọmọlanke ti nwọn ni lati ma san owo asnsan tan,

Nwọn ni pọnun mẹrindinlọgbọn ati şile kan ni awọn nsan silẹ ni Kotu ' ko ki awọn to ma gbe gb da awọn wọ wa siko lọjọ ti nwọn ba ti gba ẹwọn si awujọ awọn lọya.

Mo gbọ wipe pọnun mẹta ati şile pere ni awọn lọya kekere ti nwọn ba şẹşẹ de a ma san; awọn ti nwọn ba tise ju ọdun marun lọ lẹnu işẹ na a ma san pọnun marun ati şile marun lọdun; pọnun mẹwa ati şile mẹwa ni ti awọn lọya alagbada nla agbejọro Ọbabinrin (Q C) lọdọdun.

# First African Universities Press Books On Sale In Britain

LONDON— The first three books to be published by African Universities Press of Lagos — the first indigenous publishing house in in dependent Afirica— were on sale in Britain this week.

The British publisher, Andre Deutsch, who played a considerable part in the formation of the African Universities Press last October and is now a director of it, is acting as distributor of the books in Britain and other parts of the world

The first three titles, which have already been published in West Africa are: Reflection-Nigerian Prose and Verse, edited by Frances Ademola; "A Chronicle of Abuja", a translation from Hausa by Alhaji Hassan and Mallam Shuaibu Naibi; and "An African Night's Entertainment" a children's book by Cyprian Ekwensi.

'We have already dispatched copies of these books to other conntries including New Zealand, Australia, India Pakistan, Ceylon, the Caribbean, Hong Kong and Singapore, a spokesman for Andrew Deatsch told our correspondent yesterday.

African Universities Press will concentrate mainly the production of educational books. Forthcoming titles include Let's Look at Litrature, by Elizabeth Pryse; French for Afirica, by H F Kynaston- Shell; and You and Your Baby by Dr. WRF Collins and Dr. R O Adeniji—Jones.



## Iyawo Kan Ko Bale Re L'abe

# Adajo So Audu Sewon Odun Marun

SOKOTỌ—Eşu ko nile, ibi'ibi ni o ma nlọ, agbẹ Fulani kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Audu Anka ko ni gbagbe ọjọ ti eşu lọwọ ninu ija ti on pẹlu iyawo rẹ ja ninu abule wọn ni agbegbe Sokoto ti o fi gun iyawo rẹ na lọbẹ pa.

Ọrọ na di nkan ti awọn ọlọpa dandoka fi mu Audu lọ siwaju adajọ wipe o pa iyawo rẹ; nwọn ro ẹjọ na t ti niwaju Ọba Sokoto nwọn ni baba agbẹ Hausa yi jẹbi iku; Ọba Sokoto ni ki nwọn lọ yẹgi fun un.

Ka wi, ka fọ nwọn gbe ẹjọ na lọ si Kotu nla niwaju adajọ Oyinbo kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Ọgbẹni Holden, wipe ki o yẹ ẹjọ Audu yi wo. Nigbati adajọ yi gbe ẹjọ na yẹwo o ni ẹşẹ ti ọdaran yi şe ko le to nkan ti a le yẹgi fun un, adajọ na ni on npa a laşẹ ki o lọ şẹwọn fun ọdun marun gbako.

Irohin ti a gbọ nipa ija ti Audu ba iyawo rẹ ja ni wipe lọjọ ti awọn ja ija na iyawo Ọgbẹni na ko labẹ, o si lọ ọ ni abawiaye na, o fẹ faja,

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

IWE SI OLOTU

## Ipinle Tuntun Da ?

Ẹ jọwọ, a'agba, kinni ẹ ro nipa ọrọ awọn alabaşe wa ni agbegbe Ibinni ati Ijaw ti nwọn npe ni Mid-West ti nwọn ni awọn fẹ ya kuro ni Ipinlẹ Iwọ Orun ?

A gbọ wipe ti nwọn ba ti yọnda fun awọn ara agbegbe na lati ma lọ yanju ọrọ wọn, nwọn ni ko le pupọ fun awọn Igbomina ati awọn ara ilu ti nwọn wa ni ẹsẹ odo ilu Hausa pẹlu awọn miran ni ilu Ibo lati gba ipinlẹ ti nwọn.

Olotu, bi awọn alakoso Ijọba Apapọşe ba le se eyi fun awọn ara ilu ti nwọn nja fun ipinlẹ ti wọn lọtọ yio dara pupọ. Ki ipinlẹ kan ko ju ọkan lọ bi ti ilẹ awọn Hausa ko dara rara.

Ẹ jẹki nwọn pin ipinlẹ yoku ki aiye ko ba tutu ki a ri bi gbe.

Emi ni
Moses Adepeju
Ottun-Oro

## Iranlowo Lati Odo Awon Odo

Aworan yi ni igbati Ogbeni Nicholas Scott (eniti o wa lapa osi) tise Olori awon omo egbe odo ilu Gesi ti nwon nje Young Concervatives nfun Ogbeni S J Mfiro, Ajele ilu Tanganyika nilu London ni iwe owo ebun fun iranlowo ise awon afoju ti o wa ni ilu na; egbetala-o - din ogorun ponun (£2,500) ni gbogbo owo ti awon omo egbe na fi ta won lore fun awon agbe afoju na.

# Ibosi Ole Ni Jankara

**Lati Owo Ezikiel Atoyebi**
**Omo Samora, Igbomina**

Mo nkọ iwe yi lat kesi awọn ọga Ọlọpa (Commisioner of Police) Eko lati ba wa mojuto ibiti awọn onimotọ akero ti nwọn npe ni bọlẹkaja (motor park) nduro si ni Ọja Jankara nibi Ojo Giwa Street.

Nkan ti awọn ole ati awọn ọmọ jaguda nṣe nibẹ ko ṣe rohin rara. Ti o ba ti to nkan bi agogo mẹsan alẹ, ẹniti o ba gba ibẹ gbe, Nkan ti ẹ o kọ kiyesi ni tẹtẹ ti ẹ o ri wipe awọn ọmọ jaguda na nta, nwọn a si ma pariwo gee bi ẹni pe awọn nna ọja.

## Danadana

Ti nwon ba pari tẹtẹ (gamble) ti nwọn nta na tan, ti ọpọlọpọ wọn ba ti ju owo nu, nwọn a wa duro soju ọna lati ma pa awọn ti o ba nkọja lọ lara lati ja owo gba lọwọ ẹnikẹni lọna bayi:

Ọkan ninu awọn danadana ole na yio fi soju ọna, yio fi jingi-dudu (sunglass) ti o ti bajẹ soju, ti o ba ti ri enia kan ti o nrin bọ loju ọna, a gba a laṣo mu, a wipe o fọ jingi oju on, bẹ ọmọ jaguda yi ni o ba jingin ara rẹ jẹ; ọmọ Ole na a ma lọgun wipe a fi bi o ba san owo jingi on fuu on.

Lẹsẹkẹsẹ awọn ọmọ jaguda yoku ẹgbẹ rẹ a sare jade wa ba oluwarẹ, nwọn gba a mu, nwọn a ma wipe baba, ẹnyin na ẹ ba a wa owo jingi rẹ; tabi ẹ nfẹ ijangbọn ni?

## Jaguda Pali

Gbogbo bi nwọn ti nsọrọ ti nwọn nho gee yi, nwọn a ma fọwọ lu apo Oluwarẹ wo, awọn miran a ma tọwọ bọ ọ apo boya nwọn le ri owo gbe lọwọ oluwarẹ ti nwọn a da lọna yi.

Fun apejuwe, laipẹ yi ni awọn ọmọ jaguda oni-tẹtẹ na da ọkunriu kan ara Oke pẹlu awọn ọrẹ rẹ meji ara Ondo ti nwọn ṣẹṣẹ de lati ilu wọn lọna ni Ọja Jaukara yi. Bi awọn yẹn ti nkọja lọ ni nwọn ba pade agbako wọn.

Nwọn lu awọn mẹtẹta na ni alubolẹ, nwọn fa wọn laṣọ ya, ṣugbọn awọn ẹniti a wi yi ko mu owo lọwo rara, gbogbo aṣọ ara wọn ni nwọn gba silẹ, ihoho ni awọn ọkunrin na lọ sile wọn.

Ẹ jọwọ, a tun bẹ awọn Ọga Ọlọpa'nu (C I D) ati tode ki nwọn ma fi awọn ọlọpa sibẹ lalẹ lati wa ko awọn ọmọ jaguda yi lẹnu iṣẹ buruku ti nwọn nṣe ni alalẹ.

# E ka Oro Olowo Ojiji Loju Ewe Kefa

**Ayiluka Ni:**

# A! 'Segun! Iku Doro!

A! bawo ni ko ba tiri ti o ba jẹ wipe a ri ọna ti a e fi bẹ IKU wipe ki o jọwọ ki o ma ṣe pa ẹniti a ba nfẹ? Iku Ọgbẹni 'Ṣẹgun Awolọwọ tiṣe akọbi ọmọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti o pade agbako iku mọto ni Abule Abanla loju ọna Ibadan si Shagamu dun mi pupọ ti nko tilẹ mọ nkankan ti mo le kọ nipa rẹ ju wipe ki ntu iya ati baba ọmọ na ninu lọ ati pe ki Ọlọrun ko ṣe olutunu fun wọn, ki o si ṣe apata fun wọn, ki o da awọn yoku si.

Iku 'Ṣẹgun dun emi Ayiluka pupọ nitoripe nko ti ẹ ti foju mi kan an nigbati o ti dọkunrin, nigbati o wa lọmọde ti o nlọ si sukuru Agbeni Methodist School n'Ibadan ni mo ti foju kan an. A! 'Ṣẹgun! A! Iku! Iku nko ri ọ daji o.

Ẹnikẹni ti o ba ri iyawo Oloye Awolọwọ ni ọjọ ti nwọn tufọ ọmọ rẹ fun un a kanu abiyamọ, ṣugbọn iya ọmọ na fi gbogbo wahala na le Olọrun lọwọ, o ni on nikan kọ ni a kọ ri idanwo laiye; omiran ọrọ Woli JOBU ti iwe mimọ BIBELI sọ itan iru idanwo ti o ri nigba aiye rẹ. Nitotọ ẹniti Ọlọrun ba fẹ gbega ni o ndanwo. Oluwa ko dawọ idanwo yi duro fun idile Awolọwọaṣẹ.

## Owo Isolenu Wo'lu

Ẹyin ti ẹ fẹran ara yin, ti ẹ ko tan ara yin jẹ, ti ẹ ma ngbọ gbogbo ikilọ ti mo ba nṣe fun yin ni ọsọsẹ ni mo mba wi lọsẹ yi o! Mo ni awọn burọda mi lati Ipinlẹ tuntun ti a ṣẹṣẹ fẹ ya kuro ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti ko OWO ISỌ LẸNU KAN WỌLU ninu owo pepaa (Currency notes) ti nwọn kan jagba lọwọ awọn akọwe ile ifowopamọsi (Bank) nigbati nwọn nkọ owo tun tun kan lọ si Warri dipo owo atijọ ti a ti nna.

Awọn ọlọpa ni gbogbo ami namba ti nwọn kọ si ara iwe owo na ni nwọn yi pada si bami; eyiti nwọn kọ E si lara nwọn sọ'di B; eyiti nwọn kọ C si lara, nwọn sọọ di O. Ṣe ẹ ri oju aiye lode bayi? Awọn baba Ologogoro mọ ọna bi nwọn ti nṣe wa owo pupọ, ẹsọ dọwọ yin o.

(wo iyokn loju ewe karun)

**Owo Awon Onisuga Ilorin:**

# Awon Olopa Mu Telo Olowo Ojiji

EKO—Awọn ọlọpa ti bẹrẹsi ro ẹjọ awọn ti nwọn ji owo awọn Oyinbo onişẹ ṣuga gbe ni Ilọrin laipe yi, ninu wọn ni ọkunrin kan ti o njẹ Yesufu Bakare Yẹkinni, ti o nṣe telọ alagbaran aṣọ wa pẹlu Adesina Willoughby, Justus Ojẹkunle ati L. Okeke, awọn mẹrẹrin ni awọn ọlọpa fesun wọn sun wipe nwọn gbe ẹgbaa mẹtalelọgbọn o le adọrin din nirnwo pọn un (£66,334) lọwọ Barclays Bank l'Eko ninu oṣu June ti o kọja yi.

Wo iyoku ni oju ewe kẹfa.

# ELETI—OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, — "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL XIV. NO. 878 SATURDAY JULY 20—JULY 26 1963


# Iwe Si Olotu

## Itan Eko Akete Wu Wa

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba emi na laye lati sọ nkan ti mo ro nipa itan bi ilu Eko ti ri ni atijọ ti o ritan yin kan, Ọgbẹni Ọnatade ti ma nkọ fun wa ri, ti o npe ni Eko Akete ile Ọgbọn, ti ẹ nfi igba kan te jade fun wa ninu iwe irohin Eleti-Ọfe.

Itan na wu wa pupọ ti emi alara ti mo nkọ iwe yi ko fẹ ko tan rara. Ti mo ba ra iwe Eleti Ọfẹ nigbana, ibiti nwọn ntẹ itan na si ni mo ma ntete wo ki mba le ka a gbadun.

Mo tilẹ fi igba kan ka wọn fun iyawo ọrẹ mi kan ti o nṣe iṣẹ tisa ninu ile iwe kan ni Ebute-mẹtta ti nwọn daruko baba iya rẹ sinu Itan na, on na gbadun rẹ.

Ẹ jọwọ ẹtun ba wa tẹ iyoku itan Eko Akete ile ọgbọn na si.

Emi ni,

A. B Layiwọla
Oko Baba,
Ebute-Mẹtta

## Ilu Esie Nko ?

Olotu, jọwọ gba mi laye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Arinwa ni Kaduna lati ba awọn ara Ilu Esiẹ tun oju ọna wa ṣe, nitoripe Eruku kojẹ ki nwọn gbadun rara nibẹ, ati pe ni asiko ojo ti a wa yi ọna na ko ṣe foju kan rara.

Ilu Esiẹ ko kere labẹ Ilorin rara, Ilu Esiẹ ko kere labẹ Ilọrin rara. Ilu Esiẹ ko fi owo ori wọn jafara lati ma san fun ijọba na, Ki o tete bawa ṣe eto oju ọna wa na. Ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ o, Olotu iwaju ni ẹ o ma lọ.

Emi ni,

Gabureli Ọlabọde Anifowoṣe
Esiẹ,
Itọ Ọffa.


# Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogun ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo, ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de igbà.

**'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'**

Barclays Bank ti ṣe ọpọlọpọ aworan oni simima ti a ti mọ dada to si nderin pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Eyi jamọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti won ko eso oko wọn losi ọja. Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.





Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe ọ ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nyá owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ ibusùn, sugbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kòkoro tun jẹ iyiokù.
Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.
Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata sile Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ wọn mbẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*




# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Owa Ilesha Waja

Mo sọ ni aipẹ yi ninu ọrọ iwasu mi ninu iwe iro-hin Eleti-Ọfẹ wipe nibi ti awọn kan nsọkun ni awọn alayọ kan nyọ; boya ọrọ arofọ temi Ayiluka ta ko ye ẹnyin ọkawe mi, ẹ jọwọ ẹ jẹ ki nla diẹ fun yin ninu asaro ọrọ mi na.

Gomina Ipinlẹ Iwọ Ọrun, Ọlọla Odẹlẹyẹ Fadahunsi ati iyawo rẹ ko ni gbagbe ọjọ kẹrindilogun osu July ni ọdun 1963 nitoripe ni ọjọ na ni ọbabinrin ti ilu Gesi ti aṣọ eye ti o fi da lọla fun un. Lọjọ na gan ni Ọba ilu rẹ ni Ilesha ti a npe ni Adelupọ Ogunmokun Biladu Kẹta waja.

### Ibi Elekun Nsokun

Nibiti ẹlẹkun gbe nsọkun ni alayọ nyọ! Ọlọlọ Gomina Fadahunsi nṣe yọtọmi nilu Ọbabinrin ilu Gesi awọn ijoye Ilesha nṣe ọfọ Ọba Ọwa. Emi na mọ nkan-kan d ju, eyi ni wipe Gomina wa na ko ni gbagbe ọjọ ti Ọba ilu Gesi fun ni ẹwẹ oye rẹ ni ilu London.

Ọjọ pataki ni ọjọ Iṣẹgun (Tuesday) July 16 jẹ fun gbogbo awọn ọmọ Ọwa ati ẹru Ọwa jake jako. Mo mọ wipe awọn Olorisa ilu Ijesha ati awọn Onigbagbọ ibẹ pẹlu awọn baba Serafu ati iya Kerubu a fi ọjọ na kọrin

### Alayo Nyo

I o gbọ wipe Keyinde Dairo, ẹru Ọwa ti Ọbabinrin ilu Oyinbo fi oye (MBE) da lọla (I K Dairo ni ẹ npe e l'Eko) fẹ lọ ṣe ọjọ mẹdogun nilu Oyinbo. Awọn Oyinbo alawo akọrin ti nwọn njẹ DEKA (DECCA) ni nwọn ni ki o wa ki awọn.

Ko ba pẹ diẹ ni ọhun, ṣugbọn ko fẹ ki awọn ọmọ araiye gbe nkan gba ẹhin on ni. Boya ki o to wọkọ a kọ orin meji tabi mẹta fun wa nipa iku Ọba Ọwa Ogunmoku ati Ọlọla Gomina Fadahunsi.

Ọmọ Ọwa ni emi Ayiluka paapa ati pe ti a ba fẹ sinku Ọba Ọwa mo ni lati da owo akara Ijesha temi pẹlu owo ẹmu ọgọrọ. mo si tun ni lati mu odo iyan kan wa sidi Orisha Ijesha.

Mo ki gbogbo ẹnyin ara Ilesha, loko, lodo nile ati ni idalẹ, ẹ ku aṣẹhinde Ọba Ọwa

World famous

Permit us, without obligation, to show you the varied range of Mercedes-Benz cars and get to know their outstanding merits on a trial run. You can place your full confidence in these cars and in the excellent service provided by factory trained mechanics.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN. KANO. KADUNA. JOS. PORT-HARCOURT. ABA

Sub-Distributors:-

ARMELS TRANSPORT LTD.

Benin-City, Onitsha & Aba

### Abule Ogogoro

Mo gbọ wipe Oloye kan l'Eko pe awọn Ijaw (Ijọ) ti nwọn ngbe abule kan ti nwọn npe ni OGOGORO leti Okun mọ odo Ọsa lẹjọ wipe ki nwọn kuro lori ilẹ awọn, awọn fẹ lo ilẹ na.

Awọn Ijọ paapa ti nwọn wa ni abule na tilẹ ti mura lati ko iṣẹ wọn lọ si ilu wọn nitoripe awọn na ti gba ominira ninu Satide ọsẹ ti o kọja yi. Iṣẹ ọti ogogoro paapa ko tilẹ kuta ni Warri. Bi enia ba pọn ọti na tan ni Bomadi bi ko ba ri ero ra pupo larọkọ, o le ru u wa si Benin City tabi koi gbe Ṣago rẹ wa si Asaba ki nwọn ri nkan mu lọjọ ti nwọn ba fẹ ṣe ajọyọ ipinlẹ tuntun ti nwọn fẹ ṣe laipẹ yi.

Ọba Akenzua ni ilu Benni (Binni) ni emi Ayiluka ba yọ pupọ lori ọrọ ipinlẹ tuntun na nitoripe gbogbo igbin ati ikarawun ilu rẹ ni nwọn yio ra tan patapata.

# Obo Ni Yio Pa Ara Re

Ọrọ behin yọ, awọn Oyinbo ijọba isalẹ Afrika (South Africa) ni awọn ko ni bi wọn dawo si ipade ero gbogbo agbaiye mọ nitori ati ko ti Ijọba enia dudu nta ko wọn lori ọrọ aṣọ enia dudu ti nwọn ni awọn nṣe ikorira ọmọ iya wọn.

Ogun ti Ijọba awọn enia dudu gbe ko awọn Oyinbo ti o mba wa gbe ni-salẹ Afrika yi pọ, emi Ayiluka gbọ wipe awọn enia dudu kan ni wọn ko fẹ fẹ ri ọkọ eropileni wọn ati ọkọ oju omi wọn ni ebute awọn mọ rara. Nwọn ni ni ebi ni nwọn yio fi pa gbogbo awọn Oyinbo ti o nfi ija jẹ awọn alawọ dudu yi. Ọbọ ni yio pa ara rẹ nitotọ.

Esin Tafawa Ko Je'ko:

# Oloye Bayo Doherty Ga Ju Won Lo

LONDON — Iwe idajọ ẹjọ ko-tẹmilọrun ti awọn alakoso Ijọba Apapọṣe gbe lọ si ilu Oyinbo lori ọrọ ile ifowopamọ National Bank of Nigeria ti Ọlọla Tafawa Balewa, Olotu Ijọ-Apapọṣe na, fi igba kan paṣẹ yan awọn enia kan wipe ki nwọn ṣe iwadi (ẹnkuari) iṣẹ ile ifowopa-na, ṣẹṣẹ jade, awọn adajọ ogunagbongbo ti nwọn ro ẹjọ na niwaju wọn ni awọn faramọ idajọ ti adajọ ti Adajọ-agba kan, Ọgbẹni Daddy Onyeama kọkọ da l'Eko, ti o ni ofin ko wipe ki awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe maṣe atojubọ ile ifowopasi na.

Nigbati ọrọ a-fẹ-ṣe iwadi ile ifowo pamọ si na kọ bẹrẹ ni iwọn ọkan bi ọdun keji sẹhin, Oloye Adebayọ Doherty tiṣe oludari-agba ile ifowopamọ na ni o kọ wọ Ijọba Apapọṣe lọ si Kotu ganran wipe ofin ko fun wọn ni agbara lati tojutọ ile iṣẹ awọn; awọn ti nwọn yan wipe ki nwọn ṣe iwadi na ti de lati ilu Oyinbo, nwọn si ti bẹrẹsi ṣe iwadi na lọwọ ki Adajọ-agba Daddy Onyeama to paṣẹ lati da wọn duro.

Lori idajọ yi ni Dokita Elias tiṣe Olotu amofin Ijọba faake kọri, nwọn si tun gbe ẹjọ na loruko Alakoso Ijọba Apapọṣe lọ si ilu Oyinbo wipe ki awọn ogunagbongbo adajọ kotu nla kotẹmilọrun ba awọn yẹ ẹ wo. Awọn adajọ kotu kotẹmilọrun na si tu ẹjọ na ka, nwọn ni awọn faramọ ẹjọ ti nwọn da wọn l'Eko lori ọrọ ile ifowopamọsi na. Nwọn ni ki nwọn lọ san owo irin ẹsẹ fun Oloye Doherty, ti gbọn nwọn ko ti ṣiro gbogbo iye ti owo irin ẹsẹ na yio ku si.



AKIYESI- O dun wa ti ẹnyin ọkawe wa ko ri irohin yi ka ninu irohin wa ti ọsẹ ti o kọja lọ, aye ni ko si fun wa nigbana lati tẹ ẹ jade nigbana. Ẹ jọwọ, ẹ ṣe gafara fun wa. OLOTU

**BE TALLER**
Increase your Height.
Details free. Add:-
C. T. Hospital, Azad Market,
Delhi 6, India.

Owo Awon Onisuga Ilorin:

## Awon Olopa Mu Telo Olowo Ojiji

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Agbẹjọro Ijọba, Ọgbẹni G. C. Nonyelu ni larin ijọ kẹta ti awọn ji owo na ni ile ifowopamọsi, baba telọ olowo ojiji yi sare fi owo orisirisi pamọ si ile ifowopamọsi meji. O ni larin ọjọ mẹta, ẹgbawa pọnun (£20,000) ni o fi pamọ kakiri.

Agbẹjọro Ijọba na ni nigbati nwọn bi Yẹkinni telọ yi wipe nibo ni o ti ri owo ojiji bayi, o ni owo ile awọn ti awọn ta ni Apapa Ajegunlẹ ni on fẹ fi pamọ lati ri lo fun ile tuntun ti awọn fẹ tun ra.

Ọrọ baba tẹlọ olowo ojiji yi ko duro nibikan, o tun sọ fun awọn ẹlomiran wipe awọn kan ni nwọn pẹlu on ti awọn da ẹgbẹ onisowo kan silẹ, o ni ọkẹ mẹwa pọnun (£200,000) ni owo ti awọn da lati ma fi ṣe iṣẹ owo na.

Eleyi jẹki awọn akọwe ile ifowopamọsi fura sii, nwọn si mọ wipe ninu owo awọn Oyinbo onisẹ ṣuga ti nwọn fi ọna eru gba ninu ile Banki ti a darukọ l'Eko yi ni ọdaran olowo ojiji yi nfi eyiti awọn ọga rẹ pipin pamọ kiri.

Agbẹjọro ọba ni awọn fẹ ki adajọ paṣẹ wipe ki awọn gba gbogbo owo ti o ko pamọ si ile ifowopamọsi lọwọ rẹ.

O tun ṣe alaye siwaju wipe o ku awọn enia meji pataki kan ti nwọn jẹ babasalẹ, ti nwọn ṣe ọna ti nwọn fi ri owo na gbe ti awọn ọlọpa fẹ mu wa siwaju adajọ, nitorina ki adajọ maṣe gba iduro awọn ọdaran na titi awọn yio fi ri wọn ko wa si Kotu.

• **HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.*

**HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England**

## Okunrin Kan Gba Busun Bedi Lowo Ale Re

APAPA AJAGUNLẸ — Ọkunrin tiṣa kan ti nwọn npe ni Frank Okemin ni awọn Ọlọpa wọ wa siwaju adajọ wipe o ji busun bẹdi kan gbe nile obinrin kan ti oruko rẹ njẹ Grace Nkano loru ọjọ kan; awọn Ọlọpa ni pọnun meje pere ni ọmọge obinrin na fi ra busun bẹdi na.

Nigbati awọn Ọlọpa wọ Ọgbẹni na de iwaju adajọ, ti nwọn ka ẹsun rẹ fun un, o ni on ko jẹbi rara, o ni on ni on fi owo ra ibusun bẹdi na, o ni ọrẹ ni on yan Grace, nigbati ko ri ibusun sun ninu iyara ti o haya ni o ni ki on ya on ni ti on.

Awọn Ọlọpa ni nkan ti awọn gbọ nipa ẹjọ na ni wipe loru ọjọ ti Grace, ọmọbinrin ti o ni busun bẹdi na ko si nile, ti o lọ sun lọdọ ọkunrin miran ni Tiṣa yi wọ iyara rẹ lọ, ti o si palẹmọ bẹdi na.

Adajọ ti sun ọjọ ti yio gbọ gbogbo idi ọrọ ẹjọ na siwaju ninu oṣu ti mbọ yi.

# Nigerian Traders Will Now Buy Goods From Russia

## But No Credit Facility

MOSCOW—For the first time in Nigeria history, her citizens, under an agreement signed recently in Moscow by Federal Minister of Commerce and Industry, Alhaji Zanna Bukar Dipcharima, who left Russia for Lagos having signed first trade agreement on behalf of Nigeria with the Soviet Union, will now be able to buy goods from that country.

Before his departure the Minister said that under the agreement Russia would buy our groundnuts, palm oil, and cotton in return of Soviet consumer goods and farming implements.

Our correspondent indicates 'no question of any credit being granted by the Soviet Union, even I guaranteed that our government did not ask for this facility".

Meanwhile, all the trade pacts with other continental countries are yielding turnover of several million pounds annually. It is understood that Soviet Union own might be larger considering the size of the country.



Alhaji DIPCHARIMA
Federal Minister of Commerce and Industry.

## News All Over Africa

### Jet-Engine Trading For Moroccan Engineers

Equipment for the specialised training of mechanics in the maintenance and repair work on Rolls-Royce Avon jet engines is to be supplied to the Moroccan Government's civil avaition and meterological training centre at Casablanca, by the British Department of Technical Co-operation.

### Educantion Diplomas For Kenya Teachers

Two Kenya schoolteachers, Mrs Razia Sultana Abdulla of the Muslim Girls High School Nairobi, and Miss Shirin Kassam, of the Aga Khan Primary school, Nairobi, have been awarded the Associateship in Education for Overseas Teachers at the end of their 10 month course at the Institute of Education, Durham University, England.

### Blind Training Farms For Sierra-Leone and Gambia

Farm training centres for the blind are shortly to be set up in Sierra Leone and Gambia, the Royal Commonwealth Society states in its annual report, published in London recently. The centres will be similar to those already established in Nigeria, Ghana and many other countries.

The purpose of the farm training centres is to help blind villagers to grow their own food and to see that, once trained as farmers, they are set up on their own small-holding with the necessary amount of help and advice in running them.

### Medical Research In Cameroun

The Federal Republic of Cameroun has concluded an agreement with the British Medical Research Council, which will guarantee the maintenance of British research at the Kumba Medical Centre. By agreement the salaries of the research staff will be met by the British Government.

### British Graduate Teachers For East Africa

Thirty-seven British graduate teachers are due in Kenya, Uganda and Tanganyika in September, to take up teaching appointments in secondary schools, technical institutes and universities. They have been recruited by the Voluntary Service Overseas organisation in London, to spend initially one year teaching abroad. The British Department of Technical Co-operation is spending about £100,000 this year in subsidising the cost of sending graduate and other volunteers to developing countries.

# Britons To Work In Commonwealth Universities

LONDON—A new awards scheme to enable outstanding men and women from British Universities to serve for a time in selected post in other Commonwealth Universities was announced in London on Tuesday.

News of the scheme was given to the House of Commons by the Secretary for Technical Co-operation, Mr Robert Carr.

Mr Carr said 'each award will be £1,500 a year and will be additional to the total emoluments ordinarily paid to British University staff in the countries concerned. The first award will be made in 1964

Overseas Universities are being consulted about the post they would like to filled in this way.

I am also, of course, consulting British Universities and Academic Institutions, and I am confident that they will give their full co-operation in arraging for the selection and secondment of people of high distinction.

'I hope this scheme will be seen as a further indication of the importance the British Government attaches to service overseas.

### Britain's Overseas Aid Goes to Africa

LONDON-More than half of Britain's technical aid to developing countries this year will go to Africa.

The British Secretary for Technical Co—operation, Mr Robert Carr, told the Commons this in a written reply to a question from Mr Reginald Prentice (Labour) on Tuesday.

'This year my Department expects to give about 16 percent of its assistance to Asia, 57 percent to Africa, one percent to South America and eight percent to other parts of the world.

## Ogun Oyinbo Soro Ra L'Onitsha????

# Awon Dokita Faake Kori Lori Eto Iwosan Eko

ONITSHA—Awọn onișowo ko jọ dokita Oyinbo' ko lọ babaṣẹgun ti nwọn nta egbogi 'Oyinbo' agbe ese pọju ni ọja Onitsha ti nwọn nta egbogi ti nwọn gb'oko ṣe kiri fu awọn enia. Egbogi agbelẹse bayi ti awọn ọlọpa ri ko lọ na lana ju ẹlẹgbẹdọgbọn pọnun (£5,000) lọ, orișiriși si ni wọn, nwọn bẹrẹ lori ogun ti nwọn fi nwa ikọ awọn ọmọde titi ti o fi de ogun ẹfọri ati awọn egbogi ti nwọn ntu sinu igo abẹrẹ

Awọn Oyinbo ti o nta egbogi ni awọn enia buruku yi ti o nṣe iṣẹ na jẹ mọ awọn lọwọ tobẹ ẹ ti awọn fi ranṣẹ si awọn Oyinbo wipe ki awọn ran enia kan ti o le yọ awọn ninu iṣẹ buruku ti awọn kan ni Ila Orun nṣe lori egbogi Oyinbo.

Ọgbẹni V S Little, Oyinbo ti o mọ nkan nipa egbogi a-ṣe ta ti nwọn ran wa na ti ba ọkọ ofurufu gunlẹ, o si ti bẹrẹsi ba wọn ṣe ṣe awari awọn kiri lọja.

Ọgbẹni Oyinbo na ni gbogbo egbogi ti awọn ri ni nwọn jẹ agbelẹse, ṣugbọn iwe awọn Oyinbo ti o ṣe wọn nilu Oyinbo ni wọn lẹ mọ igo wọn lara. Oni awọn ko le sọ bawo ni nwọn ṣe nri iwe lebẹli wọnyi lo.

Ju gbogbo rẹ lọ awọn ọlọpa ti mbere lọwọ awọn baba ele ogi wipe nibo ni nwọn ra wọn, nwọn ni awọn ko mọ awọn ti awọn a wọn lọwọ rẹ awọn ọlọpa si wa lẹnu iwadi ọrọ na.

# Okotie-Eboh Se Ojobi Re



Oloye Festus Samuel Okotie-Ebo ti iṣe alakoso eto inawo Ijọba Apapọṣe di ọmọ ọdun mọkanlelaadọta ni ijẹta ti ṣe ọjọ kejidinlogun yi. Oloye Okotie Ebo rẹ ọpọlọpọ awọn gbajumọ lati ba ṣe ajọyọ yi, ngbati o ba awọn gbajumọ sọrọ, o ni inu on dun pupọ nitoripe ohun ti on nreti bọ si, nipa dida ipinlẹ ti awọn silẹ, iyẹn ni Ipinlẹ Mid-West ti awọn ara agbegbe na dibo pe awọn fẹ ki Ijọba da silẹ. A ki Oloye Okotie-Ebo pe o ku ori re ọmi a ṣe ọpọ rẹ li alafia.

ETO IWOSAN ILU EKO

## Awon Dokita Oyinbo Fa ke Kori

EKO—Ọrọ ko parwọ! gbogbo awọn ọmọ egbe dokita Oloyinbo ti nwọn mbẹ nilu Eko, Ebute-Metta ati Yaba fi ake kọri ninu ipade ti nwọn ṣe laipẹ yi ninu ile ipade wọn ni Ebute-metta lori eto ilera tuntun fun awọn ara Eko ati gbogbo awọn oṣiṣẹ ti o wa ni Eko ti Minista Dokita Moses Adekoye Majẹkodunmi lẹ gbe jade. Ipinnu yi ni nwọn sọ fun gbogbo awọn oniwe irohin ilu Eko ni owurọ ana nigbati nwọn mba wọn ṣe ipade.

Gẹgebi eto ilera tuntun na ti Minista alamojuto eto ilera ti fi igba kan gbe si iwaju awọn aṣofin ninu ile Igbimọ, ti nwọn ni ki o si gbe pamọ na ki awọn ara ilu pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ dokita jiroro lori rẹ nwọn ni awọn lakọkọ Ijọba Apapọṣe Nigeria ti fi igbe kan de Dokita kan ti orukọ rẹ njẹ H.S Halevi wipe ki o ba awọn jiroro bawo ni awọn ṣe le ṣe ti ọrọ ilera yio fi di gọọfẹ fun awọn ara ilu.

Awọn dokita ile Nigeria ni awọn ri si ọrọ Dokita Halevi, ṣugbọn o dabi ẹnipe eto rẹ ti fẹ gbe jade na ana awọn ara ilu lowo pupọju; ti nwọn ba fẹ ṣe eto rẹ ni ore o to o ... ni ọna lọkere.

Ọ ... awọn oniwe irohin ni o bere ọ'ọ ... na ... ma gbọ nara iwe yi ni ọsẹ ti mbọ.

# Eleti-Ofe D'araba

## Adeshina Oba Alake Tuntun De!

(Ọ ... lọja ewe kinni)

nitoripe on ni awọn AIYE nfẹ wipe ki o jẹ Ọba l'Ake Ọga awọn aṣogbo ni

Ọmọba Adeṣina, o si fẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ọba Gbadebọ ọmọ Efunwonmi ti waja ni iwọn nkan bi ọdun mẹtalelogbọji sehin. Ọpọlọpọ awọn Ẹgba ni nwọn sọ wipe igba baba rẹ tu awọn lara pupọ.

Ayiluka Eleti—Ọfẹ a sọrọ lori oye Ọba Alake tuntun ni ọsẹ ti mbọ.

## Awon Akeko Ko Ahmadu Bello

ZARIA — O ju ọgọrun awọn ọmọ Akẹkọ ilewe giga julọ ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ nibi ti nwọn npe ni Ahmadu Bello University ti nwọn ko ri ile gbe ninu ọgba ile ẹkọ ninu awọn ọmọ ti nwọn ṣẹṣẹ gba lati ma kọ ẹkọ.

A gbọ wipe nwọn ṣẹṣẹ nwa ile ti awọn akẹkọ na a ma gbe larin ilu Zaria fun awọn ni Busọ dali mejọ gbako si ni ibiti nwọn ngbe kọ ile iwe si si fi jinna si Zaria.

Oga akọwe ilewe na ti orukọ rẹ njẹ Dowu Ona ni awọn akẹkọ ti nwọn fẹ jade lọdun ti mbọ ni awọn ri iyara fun ninu ọgba ile ẹkọ na.

## Rile Gbe Nilewe

## Ijoba Ilu Moroko Da Awon Alatako Sewon

CASABLANCA — A gbọ irohin pajawiri kan ni oru ana ni wipe awọn alakoso Ijọba ilu kan ti nwọn npe ni Moroko (Morocco) ni oke Afirika da ọgọrun ẹn'a ninu awọn ọmọ ẹgbẹ alatako oṣelu na sẹwọn lai mọ nkan ti nwọn ṣe lẹṣẹ.

Gẹgebi awọn onirohin agbaiye, ogun enia ni nwọn jẹ awọn aṣoju ile igbimọ aṣofin ilu na ninu awọn ti nwọn mu ti awọn da sẹwọn na, ko si si ẹniti o mọ nkakan ti nwọn ṣe ki nwọn to, pase wipe ki nwọn lọ ti wọn mọle.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street,Lagos, Box 467
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15,Kosọkọ Street, Lagos